Àjọ
Tourette
Tí Ìlú Amẹ́ríkà

Ìtanilólobó. Ìwádìí. Àtìlẹ́yìn.

# 'Kí ni Àkójọpọ̀ àmì àìsàn Ìfàró Iṣan lójijì (Tourette Syndrome)?



42-40 Bell Blvd., Suite 205, Bayside, NY 11361 **Tourette.org 888-4TOURET**

1__WhatisTouretteSyndromeRerun82520_YO.indd 1 6/9/2022 12:38:18 p. m.

## Tîìkì (Ìfàro ìṣan lójijì), Àwọn ìṣiṣẹ́gbòdì Tîìkì, ati àìléra Tourette Syndrome



Tîìkì (Ìfàro ìṣan lójijì) jẹ ìyíkiri ìṣan atí òhùn tí kò ṣeé dádúró. Wọ́n jẹ́ àwọn ohun tó wọ́pọ̀ láàrín ẹgbẹ́ awọn ọmọde tí ìdàgbàsóké ninu ọpọlọ wọn kò ṣe déédé, àpapọ̀ orúkọ àìṣedéédé yì ní Ìṣiṣẹ́gbòdì Tîìkì, fún ẹnìkọ̀ọ̀kan tó baní ní àìṣedéede yii, orùkọ rẹ ńjẹ́ Tourette Syndrome, àìṣedéedé Tîìkì tí o le (Aláwọ̀ọ́ká tàbí olóhùn) àti Ìṣiṣẹ́gbòdì Tîìkì tó le tí a kò tii fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀. Ìyàtọ̀ tó wà láàrín àwọn àìsedéédé Tîìkì mẹta yi ni ìrúfẹ́ Ìfàró Iṣan lójijì (Tîìkì) tó bá wà, (aláwọ̀ọ́ká, olóhùn/oní ìró, tàbí mejeeji) ati iye ìgbà tí ìṣiṣẹ́gbòdì naa ti wà lára. Àwọn ènìyan tó ní Tourette Syndrome (TS) ti ní ó kéré tan tîìkì aláwọ̀ọ́ká méjì (moto tics) àti ó kéré tán ọ̀kan ninu àwọn àkójọpọ̀ ìfàro iṣan ohùn òjijì/oní ìró (vocal/phonic tic) láàrin ọdún kan ó lé sẹ́yìn. Ní ìyàtọ̀, awọn ẹni-kọ̀ọ̀kan tí ó ní Ìfàró Iṣan lójijì tí ó le, ní yálà Tîìkì aláwọ̀ọ́ká (moto tics) tàbí Tîìkì ti ohùn tí ó wà lára wọn fún ọdún kan ó lé ati awọn ẹni tí wọ́n ní àìṣedéédé Tîìkì tí a kò tii fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ tí ó sì ti wà lárá wọ́n fún ìgbà tí ó dín ní ọdún kan.

## Tîìkì aláwọ̀ọ́ka (motor tics)

Tîìkì aláwọ̀ọ́ka (Motor tics) jẹ́ awọn Tîìkì tí ó ń fa ìyíkiri. Àpẹrẹ awọn Tîìkì aláwọ̀ọ́ká ni ṣíṣẹ́jú pàkò, fífúnjúpọ̀, ìfàro erìgì, títẹ orí/ orí gbígbọ̀n, gígúnjìká, nína ọrùn àti nina apá. Àpẹrẹ awọn Tîìkì aláwọ̀ọ́ká tí ó le ni àkójọpọ̀ àwọn iṣan tàbí àkójọpọ̀ ìyíkiri, àwọn èyí máa ń farahàn díẹ̀díẹ̀ ati pẹ̀lú afojúsùn, (fún àpẹrẹ, títiro ẹsẹ̀, pípòòyì, fífò).

## Ìfàro iṣan òjijì ti ohùn/ìró

Ìfàro iṣan òjijì ti ohùn (ìró) jẹ àwọn tîìkì (tics) tí ó maa ń gbé ohùn jáde. Àpẹrẹ awọn tîìkì ni fífi imú run nǹkan, kíkó ọ̀nà-ọ̀fun, kíkùn-hùn-hùn, dídún ati pípariwo. Àwọn Tîìkì olóhùn tó le jẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ tabi gbólóhùn tí a dámọ̀ tabi èyí tí a kò dámọ ṣugbọn tí ó maa ń ṣẹlẹ̀ léraléra tabi lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan. Ni ìdá 10-15% àwọn ìṣẹ̀lẹ, awọn ọ̀rọ̀ lè má bójúmu (fún àpẹrẹ, ìsọkúsọ, ọ̀rọ̀ ẹ̀gàn ẹlẹ́yàmẹ̀yà, tàbí àwọn ọ̀rọ̀ mìíràn ati awọn gbólóhùn ọ̀rọ̀ tí kò ṣe ìtẹ́wọ́gbà láwùjọ). Irú Ìfàró Iṣan lójijì ti ohùn yii ni à ń pè ni koporolalia (coprolalia), èyí tí wọ́n maa ń sàfihàn tàbí bu ẹnu àtẹ́ lù lori ayelujara bii àmì TS tí ó wọ́pọ̀, sibẹsibẹ, koporolalia kò pọn dandan fún àyẹ̀wò TS ati, nigba tí TS bá ti wà lara ẹnikan, kìíṣe àmì tàbí àpẹrẹ pé yoo rì bẹ́ẹ̀ titi láíláí.

## Ìfarahàn ati bi TS ṣe lágbára tó

Ìfàro iṣan òjijì (tîikì) maa n farahan láàrín awọn ọmọde tí ọjọ́-orí wọn wà láàrín ọdun marun sí meje (5 - 7) pupọ ninu wọn maa ń ní Ìfàró Iṣan lójijì alawọka ti agbègbè orí ati ọrùn. Wọ́n maa n pọ̀ si wọ́n sì maa ń lagbara síi láàrín ọmọ ọdun mejọ sí mejila (8-12). Púpọ̀ àwọn eniyan tí ó ní TS maa ń ni ìfarahàn àyípadà nígbà tí wọn bá fẹ́ẹ̀ bàlágà tán, àwọn mìíràn tilẹ̀ maa ń bọ́ lọwọ Ìfàró Iṣan lójijì náà patapata. Díẹ̀ ninu awọn eniyan tí ó ní TS ń tẹsiwaju lati ní tîikì tí ó le, tí kò sì lọ títí tí wọ́n fi dàgbà.

Ìgbéléwọ̀n tîikì lè jẹ èyí tó mọ níwọ̀n tàbí èyí tó lé, ní ìgbà mìíràn, ó lè jẹ́ ìpalára tí ara ẹni ati àìlera. Bi tîikì ẹnikan ṣe le to tàbí bí iye igba tí ó maa ń ṣe ẹni naa maa n yípadà sí -- ìdí tí èyí fi ṣẹlẹ kìí di mímọ̀ nígbamìíràn, àti nigbamìíràn, ní ìdáhùn sí awọn kókó àtinúwa ati àtòdewá, èyí tó jẹ́ mọ, wàhálà, ìpòrúuùru, ìdùnnú, rírẹ̀, àtí àìsàn.

## Awọn eniyan melo ni TS ń pa làra?

Botilẹjẹpe a lérò pe TS ati Awọn Ìṣiṣẹ́gbòdì Tîikì (Tic Disorders) kò wọ́pọ̀ nigbakanri, o ti wá hàn gbangba pe wọ́n wọ́pọ̀. Àwọn èsì ìwádìí yàtọ̀, ṣùgbọ́n àwọn ìṣirò tó wà lọwọlọwọ fi hàn pé 1 nínú ọmọ 160 láàrín (ìdá kan 0.6%) ọdún 5 si 17 ní ilẹ̀ Amẹrika ní TS ati pe, ọ̀kan 1 nínú 100 ọmọ (ìdá kan -1%) ní TS tàbí irúfẹ́ Ìṣiṣẹ́gbòdì Tîikì mìíràn. TS ní ipa lori gbogbo awọn ẹ̀yà, ẹgbẹ́ ẹ̀yà, ati awọn ọjọ́ orí ṣugbọn ó wọ́pọ̀ láàrín awọn ọmọ ọkunrin ní ìlọ́po mẹta sí mẹrin (3-4) ju awọn ọmọbirin lọ.

## Kíni ó ń fa TS?

Ohun tí ó ń fa TS ati awọn Ìṣiṣẹ́gbòdì Tîikì kò tì di mimọ. Àwọn ohun ti n ṣe okùnfà tîikì jẹ àjogúnbá, àwọn jiini (genes) naa maa ń se okùnfà níní tîikì fún ọ̀pọ̀lọpọ, iyẹn tí kii ba se fún gbogbo eniyan pàápàá. Àyíká, ìdàgbásókè tàbí àwọn kókó mìíràn lè ṣe okùnfà àwon Ìṣiṣẹ́gbòdì yii ṣùgbón lọ́wọ́lọ́wọ́ a kò tii ṣe àfihàn asojù tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ kankan. Nitorinaa, ó ṣeéṣe kó jẹ pé àjọṣepọ̀ alágbára tó wà láàrín àbùdá ẹni ati awọn koko mìíràn tó yàtọ̀ fún onikaluku ni o ń se okùnfà ìpò-ara TS ati Ìṣiṣẹ́gbòdì Tîikì ní àgọ́ ara. Awọn ìwáàdí ìjìnlẹ̀ ti ń lọ lọ́wọ́ lati wa awọn jiini (genes) ati awọn nkan mìíràn tí ó fa idagbasoke awọn ìṣiṣẹ́gbòdì ara wọnyi.



## Bawo ni a ṣe ń ṣe àyẹ̀wò TS?

Àwọn oníṣègùn tàbí akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ òṣìṣẹ́ ètò ìléra lo maa ń ṣe àyẹ̀wò naa, àyẹ̀wò naa si maa ń dá lori ìtàn àwọn àmì àkùdé naa. Kò sí àyẹ̀wò ìṣègùn lati jẹrisi èsì àyẹ̀wò TS, ṣùgbọ́n ní àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tó ṣọ̀wọ́n, àwọn àyẹ̀wò yii lè ṣe pataki lati fagilé awọn àkùdé ara mìíràn tó farapé TS.

## Àwọn àkùdé ara mìíràn wo ló ṣeéṣe kó wáyé pẹ̀lú TS?

TS ṣábà maa ń wáyé pẹlu àkùdé iṣan ara ati awọn àkùdé ọpọlọ mìíràn, diẹ ninu wọn ti le wà ṣaájú kí wọn sì fa àìpé ara ju tîìkì (tics) fúnrararẹ̀ lọ. Àwọn àkùdé ara tí ó ṣábà maa ń wáyé papọ̀ ni ìwọ̀nyì:




- **Àrùn Àìlepọkanpọ/Àrùn Araòbalẹ̀ (ADHD) —** Ìṣòrò àìlèpọkànpọ̀, ìṣòro araòbalẹ̀, ati ìṣòro àìlegbáramú.
- **Àrùn àìlèṣàkóso ìrònú àti iṣesí ẹni [tàbí Awọn ìhùwàsí] (OCD/OCB) —** Àṣetúnṣe, èrò ọkàn tí a kò fẹ ati/tàbí awọn ìwà tí eniyan ń hù léraléra. Oríṣiríṣi ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìrònú àròkúdórógbó tàbí ìsúnniṣe ni ó wà, pẹ̀lú àníyàn tí ó pọ̀jù nípa ṣíṣe ohun "tí ó tọ̀nà," àti pẹ̀lú èrò nípa ẹ̀sìn, ìbálòpọ̀, tàbí awọn èrò ìbínú. Awọn èrò wọnyi maa ń yọrísí àwọn ìwà àìgbọdọ̀máṣe, eyiti íí̀ṣe àwọn ìwà ti a kò fẹ́ ṣùgbọ́n tí ẹni naa gbọdọ̀ hù leralera ní ọna kan pàtó.
- **Àwọn ìṣòro ẹ̀kọ́ kíkọ́ —** Awọn ìṣòro tó jẹ mọ kíkàwé, kíkọ̀wé, ìṣoro ìṣirò, àti/tàbí ṣìṣe iṣẹ́ lori awọn ìfitónilétí tí kò bá ìrònú àwùjọ mu.
- **Àwọn ìṣòro ìṣehùwà —** ìwà jàgídíjàgan, ìrunú, ìwà àtakò tàbí àwọn ìwà mìíràn tó burú láwùjọ.
- **Ìbànújẹ —** Àpọ̀jù àníyàn ṣíṣe tàbí ibẹ̀rù, pẹlu títijú lápọ̀jù àti ẹ̀rù dídáwà.
- **Awọn ìṣòro ipò ọkàn —** Àwọn akoko ìsoríkọ́ tàbí àkókò ìdùnù tí ó yọrísí àyipadà ìwà tàbí ìṣehùwà èyí tí ó yàtọ̀ pátápátá sí bí ọmọ naa ṣe maa ń hùwà tẹ́lẹ̀.
- **Àìlè hùwà tó bá àwùjọ mu ati ìṣesí láwùjọ —** Nínί ìṣòro nipa bí a ṣe le hùwà láwùjọ; bíbá awọn akẹgbẹ́ ẹni dọ̀rẹ́, awọn mọ̀lẹ́bí ati awọn ẹnìkọ̀ọ̀kan mìíràn; ati híhùwà lọ́na tí ó bá ọjọ́-orí mu.
- **Àwọn ìṣòro orun sísùn —** Iṣoro àìrí orun sùn, ibusun, títọ̀ sílé, rínrìn tàbí sísọ̀rọ̀ lójú orun.

## Bawo ni a ṣe le tọju TS ati àwọn Ìṣiṣẹ́gbòdì tîìkì mìíràn?

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, àrùn tîìkì kîiṣé ohun àrùn tó lágbára, ati pe kò nílò ìtọ́jú. Ní gbogbo ìgbà, ó ṣe pataki lati kọ ẹni tó ní àkùdé naa ati àwọn eniyan tó súnmọ́ọ ní ẹ̀kọ́ nípa àrùn TS ati lati pèsè atilẹyin tí ó yẹ ní gbogbo awọn ọ̀na (ilé-ìwé, ibi iṣẹ́, ilé).

Nígbàtí àrùn tîìkì (tics) bá di ìṣoro tàbí nígbàtí ó bá bẹ̀rẹ̀ sí dabarú ìgbésí aye ẹni lójoojúmọ́, ìtọ́jú tó jẹ mọ ti ìwà tàbí òògùn òyìnbó lè di lílò. Nitoripe alaisan kan yàtọ̀ sí òmíràn, aláìsàn naa tàbí àwọn mọ̀lẹ́bí rẹ gbọdọ ṣiṣẹ́ pẹlu oníṣègùn lati piyamọ ètò itọju tí ó yẹ. Mímọ ọ̀nà ìtọ́jú ti o múnádóko julọ lè gba àkókò díẹ̀. Oníṣègùn le gbani lámọ̀ràn lati kọ́kọ́ tọjuu àwọn àkùdé alárìnpọ̀ tí ó bá jẹ pé àkùdé yẹn ń dani láàmú tàbí tí ó bá le ju àrùn tîìkì lọ. Ó ṣábà maa ń dára lati bẹ̀rẹ̀ pẹlu ìtọ́jú tó péye, ìyẹn ìtọ́jú tí kò ṣeese kó fa àkùdé kankan sì ara.

## Kini Ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ Ìdási Ìhùwàsí fún Tîìkì (CBIT)?



A ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ ní ilé ìwòsàn meji tó yàtọ̀, Ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ Ìdási Ìhùwàsí fún Tîìkì (CBIT) jẹ ìtọ́jú aláìloògùn to ń lo àwọn ọ̀nà ìtọ́jú tó jẹ mọ yíyí ìwà ẹni pada pẹlu ẹ̀kọ́ tó ń ṣe odiwọn làákàyè ẹni àti àwọn ìdásí ìhùwà tó dá lori bi ara ṣe ń ṣiṣẹ si. CBIT pín si abala mẹta tó ṣe pataki:

(a) kìkọ̀ aláìsàn lati ní mọ̀ nípa àrùn Tîìkì síí;
(b) kìkọ̀ aláìsàn lati hùwà míràn tí ó yàtọ̀ nígbà tí wọ́n bá ní imọ̀lára pé ìṣesí tîìkì fẹ́ ṣe wọn; ati
(c) ṣíṣe àyípadà sí àwọn iṣẹ́ ojoojúmọ́ ní ọ̀nà tí ó lè ṣe ìrànwọ́ lati dín àrùn tîìkì kù

## Ìtọ́jú nipa oògùn (Pharmacotherapy) ìyẹn oogun fún àrun tîìkì atí àwọn àkùdé ara mìíràn tí wọ́n jọ́ maa ń wáyé papọ̀



Haloperidol (Haldol), pimozide (Orap), ati aripiprazole (Abilify) nìkan ni àwọn oògùn ti Àjọ tó ń rí sí Oúnjẹ ati Oògùn ní ilẹ̀ Amẹrika (FDA) fọwọ́ sí lati tọju àrùn tîìkì. Ẹwẹ̀ nitori pe gbogbo awọn oògùn mẹ́tẹ̀ẹ́ta yii ṣeeṣe kò ní agbara lati fa ọpọlọpọ àkùdé, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onísègùn maa ń bẹ̀rẹ̀ pẹlu lilo “off-label” (ìyẹn àwọn oogun tì àjọ FDA kò fọwọ́ sí lati fi tọju àrùn tîìkì) ti guanfacine tàbí clonidine. Àwọn oogun mejeeji yii ní èròjà alpha-adrenergic agonist, wọ́n sì jẹ oogun tí a fọwọ́ sí fún ìtọ́jú ẹ̀jẹ̀ ríru. Awọn oogun wọnyi ni a ti rii pe ó munadoko niwọntunwọnsi ni mímú àdínkù bá àrùn tîìkì tí ó sì báni lára mu.

Àwọn ìṣòro pẹlu awọn àkùdé tó ń wáyé papọ̀ pẹ̀lú àwọn àkùdé mìíràn bii ADHD ati OCD, maa ń nílò oògùn lati mú kí aye rọrùn lati gbé fún àwọn aláìsàn tí ó ní àrùn TS. Kìí ṣe ohun tó yani lẹ́nu pe àwọn ìtọ́jú àwọn ipò àgọ́ ara yii naa lè mú àdínkù bá àrún tîìkì. Àwọn ààmì àrùn ADHD ti àìfiyèsí, híhùwà láìronú, ati àìfarabalẹ̀ maa ń fa ìṣòro lọ́pọ̀ ìgbà fún àwọn ọmọ tí wọ́n wà ní ilé-ìwé. Àwọn oògùn amúṣẹ́yá bii methylphenidate, lè ṣiṣẹ́ fún awọn ọmọ tó ní àrùn TS ati ADHD. Àwọn oògùn mìíràn tí kìí ṣe àmúṣeya, bi guanfacine, clonidine, ati atomoxetine, lè tún jẹ́ anfani. Àwọn àṣàyàn adènà serotin (SSRIs), bii fluoxetine, sertraline, ati fluvoxamine, ń ṣiṣẹ lara àwọn awọn ọdọ ati àwọn agbalagba pẹlu àníyàn/ OCD. Àwọn àkùdé rẹ jẹ́ èyí tó ṣee faradà. Tí a bá gbà ọ́ lámọ̀ràn lati lo oògùn, rí dájú pé onísègùn naa dáhùn gbogbo àwọn ìbéèrè nípa awọn anfani ati àwọn ewu.

## Àmúṣẹyá ọpọlọ tí ó jinlẹ̀ (DBS)

Fún àwọn ọ̀ran tí ó nira jùlọ́ ti TS, Àmúṣẹyá ọpọlọ tí ó jinlẹ̀ (DBS) ni a lè lò lẹ́hìn tí gbogbo àwọn ìtọ́jú mìíràn tí ó yẹ ti kùnà. DBS jẹ ìlànà iṣẹ́ abẹ èyí tó si wà labẹ àyẹ̀wò, ẹ̀kọ́ ìjìnlẹ̀ ń lọ lori rẹ gẹgẹ bii oògùn tó munadoko.

## Ṣé àwọn ọmọ ile-iwe tí ó ní àrùn TS nílo àwọ́n ohun ẹ̀kọ́ tó yàtọ̀ bí?



Awọn aláìsàn tó ní àrùn TS ní òye gẹgẹ bi àwọn eeyan yókù se ni, ṣugbọn díẹ̀ ninu wọn lè nílò àwọn ohun ẹkọ tó yàtọ̀. Àrùn tîìkì, ADHD, OCD, ìṣòro àìlèkẹ́kọ̀ọ́, ìwà dagboru, àníyàn, ati àìsedéédé ipò-ọkàn, gbogbo àwọn wọnyi lè dí ẹ̀kọ́ kíkọ́ lọ́wọ́. Ìlò àwọn ètò ìtọ́jú tó péye ati fífààyè gbani bí ó tí yẹ ní ìyàrá ìkẹ́kọ̀ọ́ lè mú ilọsiwaju ba ètò ẹ̀kọ́ awọn ile-iwe tí wọ́n ni TS lọ́pọ̀lọpọ̀. Àwọn tí ó ní ìṣòro kíkọ́ ẹ̀kọ́ dígbà maa ń jẹ àǹfàní lilo àwọn ọ̀ná ìkẹ́kọ̀ọ́ tó bá ìṣọwọ́ kẹ́kọ̀ọ́ wọn mu.

Nigbati awọn iṣoro ile-iwe ko ba ṣeé yanjú tàbí tí kò ṣeé faradà, a lè nílò àyẹ̀wò ìgbéléwọ̀n ètò ẹ̀kọ́. Ọmọ ile-iwe tí ó ní TS lè jẹ anfani níní ètó-ẹ̀kọ́ tó yàtọ̀ kan, àwọn ètò bii ètò 504 tàbí Eto Ẹkọ Oníkálùkù (IEP). Àwọn ètò mejeeji wà labẹ ìsàkóso òfin orílẹ̀-èdè, pẹlu bí àwọn Ètò 504 se jọ mọ́ Abala 504 ti Òfin Ìmúpadàbọ̀sípò, tí Òfin fún àwọn ọmọ Aláàbọ̀-ara ní Ilẹ̀-Amẹrika ati àwọn IEP sì jọ mọ́ ofin àwọn Aláàbọ̀-Ara (IDEA). Tí ọmọ naa bá ní àkùdé lára ṣùgbọ́n tí kò nílò ètọ́ ẹ̀kọ́ tó yàtọ̀ (kìí ṣe nkan kan naa bii awọn kilasi eto-ẹkọ pataki), ẹni naa kò lè pegedé fun IEP ṣugbọn yoo ní ẹ̀tọ́ lati gba ilé ati awọn iyipada nipasẹ Eto 504 kan.

Nigba ti a ti mọ pe àrùn tîìkì jẹ èyí tí èèyan kò nípa lori rẹ, a le túmọ̀ àwọn ìwà tó jẹyọ latari àrùn tîìkì gẹgẹ bii ìwà búburú tàbí ìkùnà òbí lati kọ ọmọ daradara. Àwọn ọmọde ti wọ́n ni tîìkì yẹ kí ó ṣiṣẹ́ pẹlu àwọn olupese ilera ati akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ elétò ẹ̀kọ́ lati kọ́ awọn ilana fún ṣiṣakoso àrùn tîìkì ní iyàrá ìkàwé ati ní ilé-ìwé.

## Kíni ÀJỌ̀ TOURETTE ti ilẹ AMẸRIKA?

A dáa sílẹ̀ ní ọdún 1972, Àjọ Tourette ti ilẹ̀ Amẹrika (èyítí a mọ̀ sí Àjọ́ tí ń rí sí Tourette Syndrome, tàbí TSA) jẹ àjọ tó fi ara rẹ jìn lati mú ayé dára síi fún gbogbo ẹni tí àìléra Tourette Syndrome tàbí àwọn Ìṣiṣẹ́gbòdì tîîkì ń yọ lẹnu. Àjọ àkọ́kọ́ tó wà jákèjádò orilẹ ede tó ń ṣiṣẹ́ sin agbègbè, Àjọ naa ń ṣiṣẹ lati ṣe àgbéga ìmọ̀, wọ̀n maa ń ṣe ìwádìí ìjìnlẹ̀, wọ́n sì tún maa ń pèsè àtìlẹyìn àtìgbàdégbà fún awọn alaisan ati awọn ẹbi wọn. Àjọ Tourette Association ń ṣe ìtọ́sọ́nà fún ẹ̀ka mejilelọgbọn (32) ati àwọn ẹgbẹ́ alátìlẹyìn tó lé ni ọgọrin (80) jákèjádò orilẹ-ede. Fún àlàyé lẹ́kùnrẹ́ lori Tourette ati Ìṣiṣẹ́gbòdì Tîîkì, pe 1-888-4TOURET, ṣàbẹ̀wò sí www.tourette.org, kí o sì tẹ̀lé Ẹgbẹ́ Tourette lori Facebook, Twitter, Instagram, ati YouTube.



Àwọn àlàyé tí a pèsè ninu ìwé yii wáyé nípasẹ àtìlẹyìn/Nọmba Adehun ìfọwọ́sọwọ́pọ̀ INU38DD005375-01-00 lati Ile-iṣẹ fún Ìṣàkóso ati Ìdènà Àrùn (CDC). Àwọn ohun tí a kọ sinu ìwé jẹ́ ojúṣe ti àwọn òǹkọ̀wé nìkan ati pé kìí ṣe èròǹgbà àjọ CDC. Àwọn àlàyé tó wà ninu iwe yii wà fún itọkasi ati ìlò awọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ onisegun nikan. A fi ìwé yii han pẹ̀lú àṣẹ lati ọwọ awọn òǹkọ̀wé.

Àjọ Tourette Tí Ìlú Amẹ́ríkà

Ìtanilólobó. Ìwádìí. Àtìlẹ́yìn.

42-40 Bell Blvd., Suite 205, Bayside, NY 11361 **Tourette.org** **888-4TOURET**